# AWON DOKITA GB'OGUN TI ARUN JERUN-JERUN




SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.



# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI"L'EJO





AWOGBA Omode fun Girl, Kyl, Iliku-ehin, Orere, Re Tire Ni Re Egbogi
— 15/6 —
Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St LAGOS



VOL. No. VIII 494. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, NOVEMBER 17, 1956. KOBO MEJI (2d.)


## Dokita Gbogun Ti Arun Jerun-Jerun

SYRIA. Nile awon Kora, ni ile Syria, a gbo wipe arun jerun-jerun po ni ile na tobe ti ofi je wipe, awon obinrin npari gegebi okunrin Awon egbe W.H.O. tabi awon egbe kan ti awon je ogedegede Onisegun, ti gbogbo agbaiye lo fi ara won jin lati pana arun yi run kuro ni ilu na nitori o po nibe.

Lati inu osu March 1955 ti nwon ti bere si lo egbogi fun gbogbo enia, nitoripe arun na ko ose lara agbalagba nikan bikose lara awon omode pelu, iye enia ti nwon ye wo to egbaa medogun, sugbon edegbarun enia ni nwon ri arun yi lara re.

Ki awon Onisegun nwonyi to lo egbogi fun enikan nwon o koko fa irun ori re kuro. ati Eleha, ati Alhaja, nye ni nwon nfa irun ori won kuro.

Laika awon agbalagba, oke meji ni awon omode keke ti arun yi ko jeki nwon nirun lori. Ibujoko awon awujo Onisegun yi wa ni Brazzavile.

A gbo ninu iwe kan wipe awon omo Israeli ni Olorun koko fi arun jerun-jerun ba ja, nigbati nwon sorikikun lati tele ofin ati ilana Olodumare. Awon obinrin won pari, arun na ko si kuro larin won titi di oni yi, on na ni awon ojogbon *Onisegun* gbogun ti yi.


## THE NATIONAL BANK

## Of Nigeria Limited

Ile ifi Owo pamosi yi.
Nfi ona owo han enia
Bi o ba fe je onisowo pataki ao
ran o lowo nipa wipe ao to o
si Ona to dara, ao la oju re
si Ona owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a nse iranlowo fun
gbogbo oja ile wa ti a nta si agbaiye.

ILE ISE WA NI EKO :—
37, Marina, Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWON ASOJU WA NILU OYINBO :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.

The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


## Iwadi Banki Azikiwe

### AWON LOYA SE ALAYE ORO FUN OLUWADI

Loya Dokita Udo Udoma so wipe, oro iwadi nipa Continental Bank yi pin si ona merin (1) Owo awon Agbe ti apa Ila orun bi ogorun oke poun ti nwon ni lati ma fi se anfani fun won ti nwon si ko owo na sinu Continental Bank, je ohun ti Azikiwe ati awon isongbe re ti pinnu tele lati se. (2) Ati pe nwon ti ngbero nkan yi lati se siwaju ki Azikiwe to di Premier, agbara ti Azikiwe gba yi ni odun 1955 lo fun laye lati se ohun ti o ti ngbero lati se. (3) idi re ti Azikiwe se pinnu lati ko owo yi sinu Bank re pin si ona meta, (a) ki o le da ile ise Banki sile fun awon ise ti o da sile ati fun awon ebi re, ati fun on alara papaa. (b) Nitoripe ki akowe owo mase ri ona lati tilekun Banki re pa losu May 22nd 1955. (d) Ati nitori ki awon ile ise ti o da sile mase le fo, ki a le ma wa daruko re pe Azikiwe olowo arakuyamu. (4) Ati wipe ijoba ti o da sile ni Ila - Orun je ijoba modaru, gbogbo awon alabase re lo si je monafiki, bi ko ba si be ni, Banki yi ibati je gbese rara.

LOYA MALA - ALIYU BA OLUWADI TA PERO.

Nigbati Mala-aliyu dide soro, o wipe Ogbeni Mackena ti o nse alatako ti ni oro sinu, ko nse emiti o nfe gbo idi oro lo ni lati ma bere ejo gegebi eyiti Mackena nse yen.

Ibe ni alaga oluwadi oro na dahun pe, kinla! ki oro yen ro gba lenu re, ki o mase so isokuso ni iru eyiti yio di idajo won lowo lati se.

Alaga na tun so wipe iba san jojo bi o ba je wipe awon elejo nyin ba ti fi otito oro na han iwadi yi nitorina ki Mala - Aliyu mase fi alamo-mataro, oro ti nwon ti so ni ki o ma tele.

## ARABA IBADAN S'ALAISI

Anu se wa lati fi iwe yi se ikede pe Oloye Ogbeni Ifal bi Araba Ibadan s'osu s'alaisi ni ojo Ru, Ojo keje Belu, 1956, (7th November 1956).

Ojo ori re to nkan bi adorin-le-marun odun (75-years).
Ni ojo kokanla, ojo Aiku, Belu, (11th November 1956) ni a o ya oku re.

Aboru 'Boye 'Bo sise
Akowe Gbogbo-gbo

## Asanyan Oro

Ti Allah ni Ijoba orun ati aiye, ati ohun ti o wa ni agbedemeji won. O da ohun ti o wu, Alla si ni agbara lori ohun gbogbo.
Kuran 5 : 17

Allah ki ise anu fun eniti ko ba se anu fun eda ekeje re.
Hadis Ojise Nla Mohammed
(Ki Olorun yonu si)


TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe
Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6
Obtainable at:
A. B. AKINYEMI
39A Moloney Bridge St
LAGOS.

# Islam Ẹsin Alafia

LATI ỌWỌ Y.A. SAFI

Inu mi dun pupọ lati mu wa si eti gbọ gbogbo ẹniyin onkawe Eleti-Ọfẹ wipe lati ọsẹ yi lọ, ngo ma ba yin sọrọ nipa ẹsin Islam, ngo si ma dahun awọn ibere yin pẹlu. Nko ni sai dupẹ lọwọ Olotu Agba fun irufẹ igbaliye bayi, mo si ni ireti wipe gbogbo yin yio ba mi sọ wọpọ lati mu anfani na lo dada.

Gẹgẹbi akole mi to wa l'oke, Islam jẹ ede Larubawa eyiti itumọ rẹ jasi Ẹsin alafia. Ojiṣẹ Nla Muhammed, (Ki alafia ati ibukun Ọlọrun ma bẹ fun) si ni Ọlọrun fi ẹsin na ran. Ẹni ti o ba gba ẹsin Islam gbọ ni a npe ni Muslim, awọn ẹlomiran ma npe arawọn ni Imale, eleyi ko bọ sa rara.

Ọlọrun nikarẹ lo pe ẹsin wa ni Islam, gẹgẹ bi o ti wa ninu Kuran Mimọ, Allah wi bayi "Loni ni mo ṣe ẹsin yin ni pipe fun yin, orukọ rẹ yio si ma jẹ Islam" eleyi jẹ ọkan ninu awọn idi pataki ti Islam fi san ju awọn ẹsin yio ku lọ.

Allah sọ ninu kuran mimọ wipe "Ina Arsalna ilaikum Rasullan Shaidan alaikum kama arsalna illa Firhauna rasullan" Itumọ Dajudaju awa ti fi Ojiṣẹ kan ranṣẹ si yin, ẹniti yio jẹri lako yin, gẹgẹbi ati ran ojiṣẹ kan si Firhauna. (Al Muzzamil) Kuran 73 15 Allah tun sọ ni aye miran wipe ohun ko jẹ ojiṣẹ ede kan ni iya ri ayafi lẹhin Igbati On ba ti ran Oluk-lọ si wọn lati arin ara wọn.

Larin awọn iran pataki meji ni awọn ojiṣẹ Ọlọrun ti owa lati igba ti aiye ti ṣẹ. Iran ekinni bẹrẹ lori Isiaka titi ofi de ori Jesu Kristi (ki alafia Ọlọrun ma bẹ fun wọn), iran ekeji bẹrẹ lori Ismail akọbi Ibrahimoh titi de ọdọ ojiṣẹ nla Muhammad, (ki ikẹ ati igẹ Ọlọrun ma bẹ fun wọn) ti o fi de ori Hazrat Ghulam Ahmad ti o da ijọ Ahmaiyya silẹ, ti Isi ṣe Imam samani yi.

Awọn erişirişi ọkan lo fi ara jọ ara wọn nipa wiwa si aiye awọn Annabi nwọnyi ati Iṣẹ ti olukuluku wọn ṣe laiye, ko pin dọgba, ko ṣe alai ko fun ẹnikan. Ngo ma ṣe ẹla lori iṣẹ ati ẹkọ pataki ti wọn fi kọ ọmọ enia, olukuluku gẹgẹbi asiko tirẹ.

Gẹgẹbi mo ti sọ ni iṣaju, Islam ni ẹsin wa. Itumọ Islam jasi ẹsin alafia, ẹniti o ba gba Islam gbọ ni a npe ni Muslim, itumọ Muslim ni Onigbagbọ ododo, Ọlọrun ti karẹ lo fun wa ni orukọ nwọnyi. Ẹ o tun ma ri ọwọ mi ni ọsẹ to mbọ.

Ẹnikẹni to ba ni ibere ki o dari rẹ si Y A. Safi, c/o Eleti-Ọfẹ, 28, Kosọkọ Street, P. O. Box 467, Lagos.

## Ilu ti a le ri nkan ra.

Awọn nkan nwọnyi ni a fi ibiti a nri wọn ra pupọ sinalẹ yi, diẹ ninu wọn niwọnyi.

Nilu Australia ni a gbe nri irun agutan pupọ ra. Ni Ceylon ni a gbe nri ewe Tea pupọ ra Ni Malaya ni a gbe nri oje Roba pupọ ra Ni Kẹnya ni a ti nri Kọfi pupọ ra. Jamaika ni a ti nri ọgẹdẹ pupọ ra. Nilẹ Nigeria ni a gbe nri epo pupa ra pupọ. Ni Rhodesia ni ati nri ewe taba pupọ ra.

Awọn nkan miran wa ti a mu wa lati ilu miran ti a ye ko si lati kọ iwe rẹ silẹ.

## Tal'o to Lati Ma Sin Jesu Tabi Olorun ?

LATI ỌWỌ LEMỌMU AJAKUTA

Nigbagbogbo ni mo ngbọ lẹnu awọn Onigbagbọ miran wipe, awọn nsin Jesu. Nje mo bere lọwọ ẹnyin Onigbagbọ, tale ye lati ma sin, Jesu tabi Olorun?

Ninu iwe Rome 14:18 Johanu 12:25 Paul sọ fun awọn ara Rome pe, ẹniti o ba nsin Kristi lo je itẹwọgba lọdọ Ọlọrun, ti o si nfẹ lọdọ enia. Nwọn ni Jesu sọ pe ẹniti o ba nsin mi, ki o ma tọ mi lẹhin.

Ẹjẹ ki a ṣe itumọ ọrọ ti nwọn ṣiṣe yi Ede Oyinbo sọ pe (Serve) ede Oyinbo keji (Worship) itumọ ede Oyinbo ti akọkọ ni ṣe iṣẹ mi, ekeji ni ifi ori balẹ jọsin fun Ọlọrun.

Sugbọn Jesu funra rẹ sọ wipe, a ti kọwe rẹ wipe Oluwa Ọlọrun rẹ ni ki iwọ ki o ma fori balẹ fun. On nikan ni ki o ma sin.

Eyi fi han wipe pupọ ninu ọrọ ti Jesu ko sọ jade lẹnu ara rẹ ni awọn Onigbagbọ nsọ mọ Jesu, Apẹrẹ eyi ni wipe, Jesu ko fi ẹnu ara rẹ sọ wipe ọmọ Ọlọrun l'on ako si mọ ẹniti Ọlọrun sọ fun pe on l'o bi Jesu

## Tani Nje Opalaba?

Lọjọ kan ọmọ Arọni pe baba rẹ, o wipe ngbọ! baba nwọn' ni Ọpalaba lo lu ọ, ẹnitọ ba ni bi ?

Arọni dahun pe tani nje Ọpalaba niba ba ngbe? koiti sọrọ yi tan nigbati Ọpalaba yọ si Arọni o lu u o ferẹ yọ oju rẹ. Lati ọjọ na ni Arọni ba gburo Ọpalaba ko jẹ duro mọ.

## Kabba fe fara mo ile Yoruba



Awọn enia mẹrin ti a nwo nwọnyi ni awọn enia pataki mẹrin to jẹ'igi lẹhin ọgba fun awọn ara ilu Kabba, awọn ni awọn fi ọwọ sọya fun Oloye Awolọwọ wipe, Yoruba ni awọn, Orukọ Yoruba ni nwọn nje bi awọn ba si nki wọn, awọn o ki wọn kan Iṣẹdalẹ wọn ni Ile Ifẹ. Bi Yoruba ba nsọrọ,, nwọn ko ni wa ogbufọ ki nwọn to gbọ, ọna wọn ni awọn gba fi ba ọmọ Kawo-aganni tan. Nitorina awọn gba ti Awolọwọ, awọn si mba lọ si arin ọmọ iya wọn.


## Ogun Aran (Ọjọ Inu)

Aradan Worm Expeller jẹ ogun aran pataki fun ọmọde ati agba ọkunrin ati obinrin. Ra igo kan lati le gbogbo awọn aran buburu ti o nba ọ ja ninu danu. Bi o ti npa aran, bẹni o npa eyin wọn. Wa ra tirẹ ki o to tan. Igo kan jẹ 2/6d. Owo-Ọkọ si jẹ 1/-.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES,
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.



## Irora Lakuregbe

Iwosan rẹ lododo niyi. Bi enia ba nfẹ iwosan ti o daju kuro nino irora Lakuregbe, o yẹ ki o wa fi egbogi yi ko loju. Nitoripe Kindinrin oluwa rẹ ko sişẹ to o nfẹ iranlọwọ. Nitori iru amọdi bayi lati şe şegbogi DE WITTS, yio si fun enia ni igbadun ara

Kakiri aiye ni egbogi yi ti nşe iwosan Lakuregbe, danwo, ki o lọ ra ọkan ni şọbu egbogi.



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba şise tara, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio desi oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Danwo lo ra ni sobu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles

## Okan Hausa ko bale nitori Awo

A gbọ wipe ọkan awọn ọmọ ẹgbẹ N.P.C to wa ni Ilọrin ko balẹ nitori ẹsẹ ti Awolọwọ ngbe yi. ko ye wọn si.

Nitoripe, nwọn sọ fun wa pe, Awolọwọ tigba iwe aşẹ lati şe ipade ni Ilọrin Ọffa, ati ni Oro fun awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre to mbẹ ninu awọn ilu na ati fun awọn Ilọrin Talaka Parapọ.

Ohun ti a tun gbọ ni wipe awọn ẹgbẹ Hausa fẹ sisin ku, nwọn nfi ọwọ ra imu, idi rẹ ni wipe, ni asiko igba ti ẹgbẹ Ilọrin Talaka Parapọ yio ni ipade wọn gan ni N.P.C. yio ni ipade tiwọn.

Awọn akọwe ẹgbẹ na ti kọwe si Kaduna, wipe ki nwọn gba wọn nipa ohun ti awọn fẹ şe na. A si gbọ pe awọn alaşẹ ijọba Oke Ọya ti şe ikilọ fun Sardauna wipe ki o ma şe bẹ. bibẹkọ yio lu'fin. Sardauna si ti gbomi suru mu nisisiyi.

**E ma ka iwe irohin Eleti-Ofe. Ki e si ma polowo oja nyin sinu re nigba gbogbo.**


*Gbogbo awọn ẹbi ni i ma a mu*
**OVALTINE**



nitoripe Ovaltine jẹ onjẹ mimu pataki fun ilera, agbara ati okun-inu. Eyi ti nwọn fi ẹyin, irugbin ati wara şe ni ọna ọgbọn-ẹrọ, pelu awọn nkan to nmu enia lagbara Ovaltine jẹ onjẹ ti o pe, ti o si nfun ọmọde ati agba ni okun bakanna. O nmu awọn ọmọ-ọwọ ati awọn ọmọde dagba pẹlu agbara ati okun, o nfun awọn agbalagba ọkunrin ati obirin ni agbara titun ati okun-inu; a si ma jẹki enia sun pelu igbadun, gbogbo ebi ni o nfun ni igbadun ilera ati inu didun.





**OVALTINE**
ONJE MIMU PATAKI NI



*Jeki awon ebi re ma a mu OVALTINE ni akoko onje ati nigbati nwon ba fe lo sun.*



# E L E T I Ọ F E

A-NJU-WỌN KO SE WI L'TJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

28, Kosoko Street, Lagos
P. O. Box 467

" ELETI - ỌFE LAGOS "
Phone 23370

VOL. VIII. NO. 494, LAGOS, SATURDAY NOV, 17. 1956.


## Ọmọ Eni Ni Nj'ogun Eni

Ọrọ ọmọ, ki iṣe ọrọ yẹpẹrẹ, nitori ọmọ bibi fun gbogbo orilẹ-ede to wa labẹ ọrun, papa fun awa Yoruba, o si jẹ ohun ribiribi fun Ijọba ki Ijọba nitoripe bi ko ba si enia, ibaṣe ọkunrin tabi obinrin nilu o ṣoro ki inu Ijọba ilu bẹ to le dun, nitoripe enia ni Ijọba njọba le l'ori. ki iṣe ẹranko tabi igi ati ọpẹ.

Gẹgẹbi a ti le sọ wipe iwa adọnkia, (I don't care) ati iwa agbere bu-aya, to le gongo nilu awọn Oyinbo to ni, sibẹsibẹ ọgọrọ aimọye Oyinbo l'o mbẹ nibẹ ti ọrọ ọmọ jẹ ohun ẹdun ọkan wọn, a tilẹ ri awọn iya tabi baba miran ti nwọn ko kọ lati fi ẹmi wọn le'lẹ fun awọn ọmọ wọn nibẹ, ti o ba di kara-ngida.

Melomelo ni aṣẹṣẹ le sọ niti awa enia dudu ti o jẹ wipe a ki ko iyan ọmọ nini kere: nitotọ, owo ni ẹgbọn, ọmọ ni aburo, ṣugbọn olowo enia miran mbẹ ti o jẹ wipe o ni idawọkọ diẹ nipa ẹbun Oluwa yi ti o ṣọwọn lori atẹ ita'ja l'ọja ti olowo eala bẹ ko kọ lati bana gbogbo owo ti o ni, ki o wa nipo ẹniti ao ma ki wipe ara ọmọde kole bi ?

Tani iru ibere ilẹ bayi ki wu ninu awọn obinrin? kosi, ẹnikeji. Ọmọ iya wa, ọrọ ọmọ kori bẹ! ki Olodumare, baba alanu julọ maṣai fun olukuluku wa ni ọmọ anfani, ọmọ ti yio gb'ẹhin-tun-ẹhin ṣe. amin

Ọrọ ọmọ toto fun u, ọrọ ọmọ janto-janto.


### IRIN AJO

Enikẹni ti o ba fẹ rin irin ajo, yala lenu iṣẹ tabi fun faaji lọ si ibikibi ni apa ilẹ Nigeria, tabi lọ si apa ilẹ Iwọ-Orun Africa tabi lọ si ibikibi ni agbaiye.

WA BERE

Lọdọ awọn AMỌNA irin ajo, yala lori omi, l'ofurufu tabi lori ilẹ ninu ọkọ Reluwe.

Jẹki a ba ọ ṣe gbogbo wahala rẹ nipa Iwe aṣẹ fun Irin ajo (Passports) Iwe Ọkọ-ilẹ (Tickets) aye ijoko si ati ifọkanbalẹ jamba (Insurance).

Ao ba ero Mẹka ṣeto Ọkọ pẹlu irọrun, Iranṣẹ ni ajẹ fun ọ lo wa.

**West African Travel Agency Co.**
9, Victoria Street, Box 581
LAGOS PHONE 23237


## Dawodu oba Ede goke Alo

ẸDẸ. Irohin kan wa lati ilu Ede pe Memudu Lagunju, ẹniti on pẹlu Laoye ti o nṣe ọba Timi Ẹdẹ fa kokowa mọ ara wọn lọwọ lori ẹniti oye ọba Timi Ẹdẹ tọsi, agbaregbabọ ọrọ na, ti o wa jẹ wipe La ye ni o jare ọrọ na. Memudu na ni a gbọ wipe o file aiye silẹ nigbati o di ẹni ọdun marun-din-ladọrun.

Ẹsẹ awọn mosulumi ilu Ẹdẹ lọ pe sibi oku Dawodu ilu yi, Lemomu Alimi ti o nṣe Immam Jamiu Ẹdẹ lo kirun si oku na lara, awọn Lemọmu Ratibi lo ṣe isọngbe rẹ.

Gbogbo awọn ẹbi ọba ati awọn ijoye lo pejupẹsẹ sibi oku na. Latinwo olori awọn ọmọba lo ṣe aṣoju fun Laoye ọba Timi-Ẹdẹ.

Ọmọ mọkanla ni Ologbe yi fi silẹ nile aiye, awọn ọmọ-mọ ko niye Akanji Lagunju ni olori awọn ọmọ ti Lagunju fi silẹ to gb'ọrun lọ.

Dawodu Dodondawa. Sunre ! Sunre!! Sunre o. !!.

## Erupe Tite Kise Ese

Olotu,

Ọgbẹni Woli kan ara Ilesha lo bere lọwọ mi wipe lati ma fi ọwọ tẹ erupẹ wadi iṣẹ Ọlọrun wo, ko ha nṣe ẹṣẹ bi ?

Idahun mi fun oluwa rẹ na ni pe ndao, ko nṣe ẹṣẹ. Ninu iwe Johanu ori 8, ẹsẹ 4 titi de 6, awọn enia kan wa sọdọ Jesu, nwọn wa bere nipa obinrin panṣaga kan ki nwọn le mọ eyiti nwọn o ṣe.

Nigbati nwọn bere tan, Jesu bẹrẹ o nfi ọwọ rẹ tẹ ilẹ ki o to le mọ ohun ti yio sọ fun wọn. Ẹniti o ba ka ẹsẹ ọrọ nwọnyi wo ti o ba ronu jinlẹ, yio ri ninu ero rẹ pe bi fifi ọwọ tẹ yẹpẹ wo fun enia ba jẹ iwa ẹṣẹ Jesu ko ni ṣe bẹ rara, ṣugbọn igbagbọ temi ni wipe, bi o ba jẹ ẹṣẹ ni erupẹ titẹ, Jesu ko ni ṣe bẹ.

Ninu aya Kurani sura 31 aya 34, a sọ bayi pe Ọlọrun nikan lo ni mimọ asiko ọjọ idajọ, ati yala ojo yio rọ tabi ko ni rọ, on lo si mọ ohun ti o pamọ sinu aboyun, ko si ẹniti o ni mimọ daju iru ohun ti yio ṣẹlẹ lẹhinwa-ọla, ko si ẹniti o mọ ilu ibiti on yio ku si. Ọlọrun ni Olumọ ati Oluri ohun gbogbo ti yio ṣẹlẹ.

Ninu ihinrere Mathew 24.36. Ṣugbọn nibiti ọjọ ati wakati na, ko si ẹniti o mọ ọ. Kiṣe awọn Angẹli lọrun lati mọ. Ninu ihin rere Mark 13. 32. Ṣugbọn niti ọjọ ati wakati na, ko si ẹnikan ti o mọ, ko si, kiṣe awọn angẹli ọrun pẹlu, tabi ọmọ, bikoṣe Baba nikanṣoṣo.

Lemọmu Ajakuta

## NOTICE TO CREDITORS

IN THE MATTER OF THE ESTATE OF MORADEHUN AMOPE DECEASED

Notice is hereby given that all creditors and other person having any claims or demands against the estate of Moradahun Amope late of Oke-Arin Street, Lagos who died testate on the 16th day of Sept 1955 and Probate of whose will was on the 16th day of August 1956 granted by the High Court of Lagos to Murano Ayinde Thompson and Tajudeen Akintọla Thompson the executors named in the said will are required to send in writing particulars of their claims or demands to the undersigned on or before the said excutors shall proceed to administer the estate of the deceased and distribute the assets of the said deceased among the persons entitled thereto having regard only to the claims or demands of which notice shall then have been received.

And all persons indebted to the said estate are required to make immediate payment.

Dated this 30th day of October, 1956.

A. K. I. Makanju
Solicitor to the Estate.

## Idahun Si Ibere

Ninu Iwe Irohin Eleti-Ọfẹ Oloyinmọmọ ti Satide oṣu Oct, 20th 1956 ni ibere kan ti jade wipe 'Tal'o yẹ ki o fẹ obinrin na "?

Gẹgẹbi baba iyawo ti sọ fun wọn wipe ki nwọn pade ni Afin Ọba ni ọjọ meje lẹhinti olukuluku ti ṣe iṣẹ iyanu tirẹ tan.

Nigbati ọjọ keje pe ti ẹsẹ gbogbo ilu pe si Afin Ọba, Awọlumatẹ ati Aderohunmu ni awọn ri, Olohunde kọ, ko lọ ni ọjọ na, nigbati nwọn reti rẹ titi ti nwọn kori, ọjọ ṣe nre oko alẹ, bi nwọn ti fẹ bere si sọrọ, bẹni ẹnikan sare de lati ile baba iyawo, o sọ fun wọn wipe ọmọbinrin ti nwọn ti tori rẹ pe sile Ọba ti ku nile o.

Igbọ fọ! Agan bẹ, o di ki nwọn tuka ma wa Olohunde kiri, ki nwọn to ri fẹrẹ to agogo kan oru, o sọ fun wọn pe bi o ba kan'rọn ki on wa joko ma jiroro ẹniti obinrin tọsi ninu awọn, on ko fẹ mọ, ki nwọn lọ fifun ẹniti wọn ba fẹ ninu awọn mejeji y'oku.

K'a ma fa ọrọ gun, nwọn bẹ ki o kalọ wo ọmọbinrin na, nigbati nwọn de ibẹ, o fi Ikọrun rẹ kọ l'ọrun, o si ji dide. Baba iyawo ni ko si siṣe, ko si aiṣe mọ, ki iyawo ma balọ sile rẹ, on ni ọkọ iyawo.

Abọ mi re o, ẹnyin ọkawe wa Oloyinmọmọ yi- O tun digba diẹ o.

Emi ni
Alufa Ajigbọ-t'Allah.

## A Ki So Obinrin, Obinrin L'o Nso Ara Re

Imam Kẹrẹkẹndu jẹ ẹniti ima sọ iyawo rẹ bi o ba nlọ s'ode, nitori ṣiṣọ ti ọkọ iyawo yi ma nṣọ obinrin rẹ iyawo yi lọ yan ọga Ọlọpa kan ni Ale.

Iyawo yi a ma sọ fun Lemọmu pe, nigba gbogbo bi mo ba nlọ si ode ni mo nṣe akiyesi rẹ lẹhin mi, awọn ọrẹ mi a si ma rohin fun mi pẹlu. Bi iwọ ko ba simi lati ma ṣe bẹ, ngo fi ọba han ọ.

Lemọmu kigbe wipe, Iwọ yi ewọ! tani bi ọ nilẹyi, ti iwọ yio fi l'ẹba han mi? Mẹtala rẹ ko to bẹ. Laifa ọrọ gun, Lemọmu ko yo sọ obinrin na.

Lọjọ kan, iyawo yi sọ fun ale rẹ ọga ọlọpa wipe gẹgẹbi mo ti fẹran rẹ to Bale mi ko fun mi laye lati jeki emi pẹlu rẹ gbadun ara wa, ayafi bi ẹ ba le mu ki ẹ fi pamọ fun igba diẹ. Nitori gbogbo bi mo ti nlọ kakiri yi bẹni o ntẹle mi l'ẹhin ti o si nṣọ mi. Bi o ba di lọla, ngo wa sibin ki ẹ si ma sọ lehin mi.

Bi ilẹ ti mọ obinrin na sọ fun ọkọ rẹ pe on nlọ ra nkan ọbẹ. Bi o ti jade bẹni Lemọmu gba tẹle lẹhin, Ọga Ọlọpa ati awọn Ọlọpa inu ti duro. Bi obinrin na ti kọja o ki ọga Ọlọpa, o wipe on l'ombọ lẹhin on yẹn. Awọn Ọlọpanu mu Lemọmu, nwọn bere ibiti o nlọ nwọn si fi sun ẹsun ẹniti ko niṣẹ ti o nringba-raye kiri.

Lemọmu bẹbẹ titi, sibẹ nwọn gbe ju si itimọle. Nigbati o di ọjọ kẹfa ni iyawo rẹ bari ni kotu, o wipe, Kasa! njẹ nibin lo gbe wa ti mo ti nwa ọ lati ijẹfa? O si pe Ọga ọlọpa o wipe, nitori temi, ẹ da ọkunrin yi silẹ. Ọga Ọlọpa beri o si tu ọkunrin Lemọmu na silẹ. Nṣe ni Lemọmu bẹrẹ si dupẹ lọdọ iyawo rẹ, o wipe Toto fun u. Nko tun ni sọ ọ mọ.

## A ko Gbodo Fiwe Eri Ya Enia.

O jẹ aṣa fun awọn ọpọ ẹnia lati ma ṣe mọdaru ninu iṣẹ onjẹ ojọ wọn. Ọkunrin olukọ ilewe kan ti o ti yege ninu idanwọ Iwe kẹfa ti o si ti gba Iwe ẹri pe o yege ni a gbọ pe, o lọ fi iwe ẹri tirẹ ya ọrẹ rẹ kan lati lọ fi wa iṣẹ labẹ awọn Reluwe,

Nigbati aṣiri tu, ọlọpa mu awọn mejeji yi lọ siwaju Adajọ. Adajọ na sọ wipe, iwa buruku ni iwa na bi a ba si mba ira eyi lọ, ko ni si otitọ mọ nile aiye.

Nitorina ki ẹniti o ni iwe ẹri na ti o fi ya wọn lọ si ẹwọn oṣu mẹsan, ki ẹniti nwọn fi ya lọ si ẹwọn oṣu mẹsan pẹlu iṣẹ aṣe ṣẹbadi.

**Kere o!**

A ti ni orisirisi ogun Germany to ṣeṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos

## Gesi Nro'jo Tire Nipa Ogun Egypt

Lọjọ 4th oṣu Nov ni awọn igbimọ Majẹobajẹ ṣe ipade wọn, awọn si fi ohun ṣọkan wipe, ki nwọn tete wa ọna lati fi opin si ogun ti o nja nilẹ Egypt yi.

Gẹsi ati Faranse ro o larin ara wọn wipe, ko si ọna ti nwọn le pari ogun jija yi larin Egypt ati Israẹli awọn mejeji wa ro o larin ara wọn wipe ọna to dara ti nwọn le gba ni wipe, ki nwọn lọ gba ilẹ ni ebute Suez fun igba diẹ.

OHUN TI O FA SABABI OGUN NA

Lati iwọn ọdun mẹwa sẹhin ni Egypt ati Israẹli ti wa ni ẹdekoyedo si ara wọn ti nwọn si fi ojojumọ nfa agan mọ ara wọn lọwọ lati ọdun 1949, nṣe ni Egypt nle pọnrọn wipe afori, afọrun, ayafi bi on ba ba Israẹli jagun. Lojojumọ ni awọn ẹgbẹ Majẹobajẹ njijakadi lati fi opin si ija na, sugbọn pabo ni. Ọlorun nikan lo mọ iru wahala ti Gẹsi ṣe nidi ọrọ yi pe ki ija na le pari.

Nitori ki ọrọ yi le pari ni a ṣe fi han fun Egypt wipe, ọrẹ wa l'ojẹ, a ba ṣe adehun a si yagọ fun ni agbegbe ebute Suez. Nitori ki o le mọ pe ọrẹ ni a jẹ, a tun ba ṣe adehun nipa ilẹ Sudan, eyo wa ni wipe gbogbo eyi ti a nṣe yi, yio jẹ itẹlọrun pẹlu rẹ.

Kawi, kafọ, awọn Israẹli ti sigun si ilẹ Egypt laijeki awa Gẹsi mọ, ogun wọn si ti wọ ilẹ Egypt. Ijọba Gẹsi wa ro o ni igbimọ pe, o mbọ, awọn ni a ndẹ silẹ de e.

Bi a ba wipe, ki a ṣeṣọ ma fi ẹnu sọ ọ, tani jẹbi, tani jare, ọkan yio bajẹ jọjọ, owe kan sọ wipe, bi ina ba ṣẹlẹ nibi kan ti o njo, ko nṣe wipe, nṣe ni ao ṣeṣẹ ma wa bawo ni ina na tiṣe ṣẹlẹ, bikoṣe wipe ijadu bi ao ti ṣe pana ni ao ma wa.

(wo yoku loju ewe Keje)

**Mo Gbadun Siga Pirate**



# Idahun Si Oro Woli

OLOTU.

Jọọọ gba mi laye lati dahun si ọrọ ti Lemọmu Ajakuta sọ nipa ọrọ Woli ko ṣe Woli. Ọlọrun oba ti sọ wipe, ẹnikẹni ko gbọdọ fi kun ọrọ Ọlọrun bẹni a ko gbọdọ bu u ku, ẹnikan ti o ba ṣe bẹ, titi de iran kẹwa oluwarẹ, ko ni wọ ijọ enia Ọlọrun ko si ni ri ododo ẹsin ṣe.

Gbogbo awọn ti Ọlọrun ran nişẹ ninu iwe Bibeli ti lailai, Nabiyi ni a npe wọn, lori Mohamed si ni Nabiyi pari si. Şugbọn lẹhin Mohamed ni Woli bẹrẹ.

Ki ẹ ri, oye Woli yi, ti Ọlọrun ni, ẹda kan ko le fi ẹnikan joye Woli yi, a yafi ẹni Ọlọrun ba fẹ. Pẹlu-pẹlu, ko nşe gbogbo Woliyi lo nmọ ara rẹ ni Woliyi. Ẹnikẹni ti o ba jẹ Woli, o ni lati jẹ ẹni iwa bi Ọlọrun.

O ya ni lẹnu lati ma gbọ wipe ọmọde ti agba ni a npe ni Woli kakiri ibi gbogbo ti ẹgbẹ Aladura ba wa. Njẹ, o ha cara ki enia ma purọ mọ Ọlọrun. Ẹniti "Ọlọrun ko pe ni Woliyi, ti ẹnikan ba pe oluwa rẹ ni Woliyi ti o si dahun, o purọ mọ Ọlọrun nuni. O da mi loju pe, ko si ẹniti o jẹ mọ lẹwa, ko yan a rua, ki o ma pe ara rẹ ni oruko oye K. C. M. G. ki iya gbigbona maşe jẹ oluwarẹ.

Iyalẹnu ni o jẹ fun ẹnikẹni lati gbọ wipe nwọn nkọ işẹ Woliyi ni Ijẹbu-Ode ati ni Okepopo l'Eko nihin lọdọ awọn Woliyi aladura ti Serafu.

Kiniyo oriran, Imale oriran, Aborişa nri, Ẹmi mimọ lo ngbe awọn Onibori lulẹ, Ẹmi mimọ lo nmu enia wọ igbo lọ. Ajija pẹlu jẹ Ẹmi mimọ. Kini işẹ ti ẹ şe fun Ọlọrun ti ẹ fi gboju-gbaiya pe ara nyin ni Woliyi? kini eyiyi fi yatọ si ẹsin Atinga ọpọlọpọ enia lo ngbaro awọn Atinga, ohun kanna ti o nmu awọn Aladura ti nwọn npe ni Ẹmi mimo na lo nmu awọn Atinga.

Ọkunrin kan Aladura, ya lọ woran obinrin Atinga kan, ti o joko larin ọja Ijoko Ọtta, obinrin na nsọrọ ko si ẹniti o ngbọ ohun ti o nwi, o si diju rẹ mejeji. Bi Aladura yi pẹlu ẹwu adura rẹ ti yọju si ibẹ lẹsẹkanna, o bẹrẹ si gbọn, awọn mejeji ngbede ara wọn, kini iyatọ.

Emi ni,

Rev. Akeremado.

ooooooooooooooooooooo

# Die ninu awon asise inu Bibeli niwonyi

OLOTU.

Ọpọ enia lo ti bi mi lere wipe, eşe ti a ko fi yi awọn ọrọ inu Kuran pada si ede Yoruba? Mo ti fun wọn lesi rẹ, şugbọn mo tun fẹ fi idi abajọ han ti ko jẹki a le yi ede inu Kuran pada si Yoruba.

Ọlọrun lo sọ gbogbo ọrọ inu Kuran jade lati ẹnu ara rẹ. Ko si fẹ ki ẹnikẹni yi ọrọ Rẹ pada, bẹni ko fẹ ki a fi kun. Ẹniti o ba si şe bẹ, o jẹbi si ofin Ọlọrun, iya nla ni yio si fi jẹ oluwa rẹ.

Ede Larubawa, ede Heberu, ọkanna ni wọn, ti ekinni ba nsọrọ, ekeji ko ni wa ogbufọ ki o to mọ ohun ti ekinni nwi. Şugbọn awa Yoruba, Owo ni a fi kọ awọn ede na, ko si si bi a ti le mọ sọ tọ, ko le yeni yeke-yeke bi awọn elede. Ara ohun ti mo wi ni wọnyi.

Ninu iwe Tesalonika keji 2.13, awọn Gẹsi kọ ọ bayi pe (We are bound) Şugbọn awọn Yoruba tumọ rẹ pe, awa di ajigbeşe Bawo ni itumọ Bound şe ni lati jẹ ajigbeşe itumọ ede Bound niyi, ẹnu ala, tabi pa ala, ka lọwọ ko, ati bẹ bẹ.

Tun wo inu Iwe Genesisi 16.11. nibiti nwọn gbe tumọ (affliction) si ohun aro, dipo eyiti nwọn iba fi tumọ rẹ si ipọnju.

Eksodu 4.6. awọn tumọ (Snow) si ẹgbọn owu dipo eyiti nwọn iba fi tumọ rẹ si yinyin. Iwọnyi ha ni ohun ti Ọlọrun wi bi?

Lemọmu Ajakuta

IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ewa ra QMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun ototu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE
(SILE MEJI ABO 2½d. FUN GO KAN)
O wa lọdọ :—

MMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS




BENI ! Hiho Ose Palmolive yio mu ara

RẸ RỌ YIO SI L'ẸWA

Ọşẹ Palmolive ko nlete tan, o to iye owo rẹ.

Ẹpo pupa ni a fi şe ọşẹ na, yio mu ara rẹ tutu, yio si jọlọ.

Ilu Oyinbo lati mu Ọşẹ na wa, yio to ọ lara ara rẹ yio ma dan,




Ose Palmolive nso enia di ajidewe



## Ogbeni Eyo Nki Loya Re K'abo

Eniti a nwo yi ni Ogbeni Eyo ti o nse alatako Azikiwe ninu oro iwadi Continental Bank, nigbati o nki Loya Shawcross Q.C. kabo lehin ti o pada de lekeji fun ejo iwadi Banki Azikiwe. Inu Ogbeni Eyo dun, o n pelu loya re na si fi tayo-tayo ki ara won, nwon si yo mo ara won pe, e kule, e k'abo.

## Gesi Ro'jo Tire Nipa Ogun Egypt.

(o berẹ lojo owe karoo)

Ogun ti o berẹ yi, o le di nkan ti yio kari gbogbo ilẹ Lerubawa, o si yẹ ki a tete fi opin si. Eyi ni ohun pataki to mu Gẹsi ati Faranse gbimọ pe nitori awa mejeji yi ni ọrọ na kan pupọ fun atunṣe. Ijafara lewu.

Awa mejeji da ọrọ na ro bayi pe bi a ni ki a fi ọrọ na le ọwọ ẹgbẹ Majẹobajẹ ki nwọn to da ọjọ ipade, ki nwọn to sọ ọ, nkan yio ti bajẹ pupọ. Eyi lo jẹki a ṣe gẹgẹbi a ti ṣe.

daju-daju wipe Gẹsi yio ko awọn ọmọ ogun rẹ jade kuro nilẹ Egypt, bi o ba jẹ wipe awọn ẹgbẹ Majẹobajẹ ti o mbọ wa mọjuto ilẹ na ko nigba lati fi awọn ọlọpa ti Gẹsi ati ti Faranse kun awọn ọlọpa ti o mbọ wa ṣe itọju ati ilaja fun awọn ara ilu na. Ati pẹlu Gẹsi ko ni aniyan lati ko awọn ọmọ ogun wọn kuro, titi ti ogun awọn onilaja (Majẹobajẹ) yio fi de.

Anthony Eden tun sọ pe, awọn ti gba ebute Port Sedu nwọn si ti mu ibẹ dani gbọnin-gbọin. Ati dawọ ija duro Gẹsi ko si ni ta ibọn mọ, ayafi bi nwọn ba yinbọn lu wa a ko si ni lọ siwaju tabi ki a pada kuro nibiti a gbe wa yi.

## Irohin Ogun Ile Egypt

Nipade Igbimọ nilẹ Gẹsi, Ọgbẹni Anthony Eden sọ pe, on ko le sọ

Ṣugbọn awọn ara Egypt sọ pe, niti awọn, ko si ẹniti o le ba wọn sọ wipe ki awọn maṣe yin bọn, awọn yio yin i titi Gẹsi ati Faranse yio fi kuro ni ilẹ wọn. Eyiti awọn Faranse sọ wipe ki a jẹki awọn ko awọn ọkọ ti o nṣe idina ti ko jẹki ọkọ raye kọja kuro lọna, awọn ko nigba rara.


# Vacancy

No. 161.

Applications are invited from suitably qualified Nigerians of either sex who wish to apply for appointment as Administrative Officers of the Federal Public Service in the External Affairs Branch of the Chief Secretary's Office with a view to eventual appointment to a future Nigerian Foreign Service.

Particulars in Government Notice No. 2020 in the Federation of Nigeria Official Gazette of 8th November, 1956. Applications to Secretary, Federal Public Service Commission, Private Mail Bag No. 2586, Lagos. Closing date 31st December.



# Ebun Odun Keresimesi

O nilati je owo

## 275,000/- ninu ere ije Navashakti

Ẹniti o ba yege patapata laisi aṣiṣe yio gba 255,000/-
Ẹniti ọgbọnran kini ati ekeji tirẹ ba yege yio gba 20,000/-

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | | |
| | | | |
| | | | |
| | | | |

Ṣe eto nomba lati 5 si 20 ti yio fi jẹ wipe bi a ba ṣiro rẹ s'ọtun, s'osi, s'oke s'isale, lati igun kini si ekeji ki aropọ rẹ maṣe tayọ 50.

Nọmba ti a ba ti lo nigbakan, iru rẹ ko gbọdọ pe meji, ki gbogbo ẹniti o ba fẹ danrawo ninu ije yi ki o tete fi ranṣẹ ki o to to ọjọ 15th oṣu Dec 1956 ki a fi ran ọkọ ofurufu. Eredi rẹ yio jade ni ọjọ 25th oṣu Dec 1956

Iye owo idanrawo kọkan jẹ 12/-, mẹrin 30/-, mẹrindilogun 70/-, mẹrinlelogun 90/-, mejilelogbọn 120/-.

| Last Result Total 46. | | | |
|---|---|---|---|
| 12 | 11 | 18 | 5 |
| 6 | 17 | 8 | 15 |
| 9 | 14 | 7 | 16 |
| 19 | 4 | 13 | 10 |

OFIN RẸ NIYI:- Ẹnikẹni ti o ba fẹ ṣe idanrawo le ṣe iye ti o ba fẹ. Eni to ba fẹ f'owo ranṣẹ ki o fi ra Postal order tabi Money order. Nọmba ti Gẹsi ni a lo. Ma ṣe gbagbe lati fi 1/- kun owo na fun ẹniti o ba nfe gbọ esi. Eyiti awọn aloṣe ere lie ba ṣe ni abẹ ṣe. Apọrẹ bi ao ti ṣe niyi.

Ẹ fi idanrawo yio ati owo ranṣẹ si:-

## Navashakti Office

P. O. NO. 13 ALIGARH INDIA

# Oba Ilorin so pe on ni baba Oselu

ILORIN. Agko irohin wipe Saki oba Ilorin so fun gbogbo aiye gbo wipe on ko po sodo awon oselu kokan rara on ko fi ara mo otun tabi osi.

Nitoripe gbogbo awon oselu ti o mbe ni Ilorin, omo ni nwon je fun on, on si ni baba won, beni on ko feran enikan ju ekeji lo.

Enio o ba so wipe on feran awon egbe Ile Hausa ju egbe miran lo, iro ni nwon pa mo on.

Iba enia ti on nfe nilu Ilorin ni wipe ki alafia ati idagbasoke wa larin ilu, nigbati oba so bayi tan, nse ni gbogbo enia kan sara si oba wipe Sa-a-ki.

## Ta L'o Ye K'oj'oye?

OLOTU.

Gba mi laye lati bere oro yi lodo awon okawe re ti oje ologbon, oro na ni wipe awon omo oba meta kan wa, ekini je Ologun ekeji je Arewa ati eketa Onisuru.

Nigbati Oba ku Jagunjagun ni bo sori oye oba Lehin igba na, awon meji to ku wa bere si ba ara won jijadu lori enitti yio koko bo sori oye nigbati Jagunjagun ba ku.

Nje enyin okawe wa yi, e ro o wo ninu awon meji ti o ku, Onisuru, ati Arewa, ewo lo ye ki a fi j'oye oba lehin Jagunjagun?

Emi ni
R. A. Sheetan

## IKOMO TO LARINRIN

Ogbeni Badele ni Olorun fi omo titun rubutu kan ta lore lati odo Salamotu iyawo re.

Lojo ikomo na, orisirisi obun jije bi iresi, amala, jolofu, iyan ati obe gbegiri ni awon fi se ipanu, awon ero to wa sibi ikomo na le ni adojo enia.

Die ninu awon gbajumo ti o wa sibi ikomo na ni, Ogbeni J.A. Adebayo Makoy, Tejumola, Afolabi, Adeyipo, Joseph, Oba Raphael Ajide, J. Onipede, olokuluku awon enia nwonyi lo mu egbe won dani wa.


MERCEDES-BENZ



THE 5/6 TON LORRY FOR

★ RELIABILITY AND LONG LIFE
★ LOW FUEL CONSUMPTION
★ HIGH PERFORMANCE

WITH A FULLY ORGANISED "AFTER SALES" SERVICE
AT MODERATE CHARGES
SUPERVISED BY EXPERT ENGINEERS FROM THE
MERCEDES WORKSHOPS.

LEVENTIS MOTORS
DISTRIBUTORS FOR NIGERIA


... 28 ... Street P. O. Box 457 Lagos Phone 23174